# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 874 LAGOS SATURDAY JUNE 22 JUNE 28 KOBO MEJI (2D) 1963

### Bayi Ni A Nse Nile Wa:

# Eewo Ibomiran; Tafawa Fomo Odun Metala Foko Ni Bauchi

BAUCHI — Awọn Yoruba ni "bayi, ni a nṣe nile wa, eewọ ni ni ibomiran. Lati ọjọ ti nwọn ti tẹ ilu ti nwọn npe ni Bauchi do, o dabi eni wipe nwọn ko ṣe iyawo ko dun to ti ọmọ Ọlọla Alhaji Tafawa Balewa, Olotu Ijọba Apapọṣe, ti orukọ rẹ njẹ FATUMỌ, ọmọ ọdun mẹtala ti nwọn fa fọkọ ninu ọsẹ yi r



**Fatumo omo odun metala na ti nwon gbe ni iyawo na ni o joko ni apa osi aworan yi pelu awon ore re meji, omo Sardauna Sokoto ni o wa larin awon ore meteta na.**

Ọgbẹni kan ti nwọn npe orukọ rẹ ni Alhaji Yaku-Wanka, tişe alaga Igbimọ ile iṣẹ Banki ajọda (Central Bank) l'Eko ni nwọn gbe ọmọ na ni iyawo fun. Gbogbo ojulumọ awọn enia pataki pataki ni Oke Ọya ni nwọn pe sibẹ.

Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello, Sardauna Sokoto pẹlu Otoye Wali ilu Bauchi,' Aluta Amiru ni nwọn so YIGI iyawo na, Ọgọrun pọnun ṣarai ni ọkọ iyawo na gbe wa ni owo YIGI dipo kọbọ meje abọ ti Alukurani wi.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

## Pope Paul Kefa Yio Gba Oye

Awọ Alufa Aguda Agba ṣe ikede ni oru ana lati ilu Rome wa wipe ni ọjọ ọsẹ, ọjọ mẹsan loni (June 30)ni awọn yio ṣe isin oye, ti awọn yio wọ aṣọ ati fila oye fun POPE PAUL KẸFA ti awọn ṣẹṣẹ yan fun agbaiye.

## Awon Ijo Aguda Yan Pope Tuntun

ROME — Ogun lọgọ awọn ọmọ Ijọ Ṣọṣi Aguda ti nwọn wa ni gbogbo agbaiya ni inu won dun nigbati nwọn gburo wipe awọn ogunnagbongbo alufa Padi ti nwọn npe orukọ wọn ni KADINA (Cardinals) yan Pope tuntun dipo Pope John Kẹtalelogun ti o jalaisi ninu oṣu yi:

POPE PAUL KẸFA:

(Wo yoku loju ewẹ kejọ)

## Iyawo Alarade Prest K'oko Re Sile

IKẸJA — Joan, tişe alarede Oloye Arthur Prest, ẹni ti o fi igba kan ṣe adele aṣoju Ijoba Apapọṣe ilẹ Nigeria ni ilu Oyinbo, ni a gbọ irohin wipe iyawo rẹ na ha ni iwe ikọsilẹ ni ana ni Kotu-ganran Ikẹja wipe on ko ṣe ịmọ.

Onirohin wa ni niwaju adajọ Kotu-nla Ọgbẹni C. Madarikan ni nwọn tişe ẹjọ awọn alarede na, iyawo na si sọ gbogbo ẹgbin ti oju on ri lọdọ ọkọ on yi ki on toko ẹru on kuro nile rẹ,

Joan, obinrin arẹwa alarede yi ni on ni

(Wo yoku loju ewe kejọ)

### Alapinni R'Atori :

# Egungun W'ole Ni Ilu Ibadan

IBADAN—Nwọn ni bi a ko ba ri Alapinni ọjẹ kan ko gbọdọ mu egungun jade sode, ọrọ atijọ ni ni Ibadan, nitoripe Alapinni awọn ọjẹ Ibadan ti ra atori, o tun ra ẹwa erce lati fi ṣe ọlẹlẹ fun ọdun eegun, ki awọn alakoso Ijọba Ibadan to fi ofin ge wọn wipe legungun kan ko gbọdọ mu egungun jade.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

# Baba Onise Pulu (Pools) Wo Gawu

YABA — Awon Olopa si mba oro ejo okunrin kan ti awon npe ni Anthoney Okeowo, ega onise Pulu (Pools Manager) nibiti awon gbe ata orire, ti awon ni o

so wayo lori iwe enikan ti o je owo orire lodo won, ti nwon ko ko owo re fun un, niso lowo niwaju Adajo Kan ni Yaba.

Eko ti a gbo ti awon olopa si mba odaran na ro ni wipe nigba kan enikan ti nwon npe ni Ganiyu Owoyele fi iwe orire re je egberin lo goji poun (£7,22?) lodo egbe Pan-African Pools ti Okeowo nse olotu re.

Dipo ki nwon ko owo yi fun eniti o sej orire yi awon Olopa ni Okeowo beresi yi iwe ti Ogbeni na fi ta orire na pada si buruku lati fi han wipe ko se iwe orire na daradara lati fi je owo goboyi ti o je yi.

Akowe owo, Tunji Olokodana ti o ma mba won ye iwe owo awon egbe onipulu na wo soro ni Kotu ni ijeta ki nwon to ye ojo igbejo na siwaju si.




Facts speak for themselves. This venerable veteran, a truck type Lo 2000, vintage 1934, has covered 1,367,000 miles. No doubt it would have gone on if Daimler-Benz AG had not bought it back at the ripe old age of twenty-five. Of course not every Mercedes-Benz can have such a long working life. However, all Mercedes-Benz vehicles are built to last just as much now as they were then, to give many years and many miles of trouble-free, economical service.

MERCEDES-BENZ

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, (E.B.): IBADAN: KANO: KADUNA: JOS: PORT HARCOURT: ABA.

SUB-DISTRIBUTORS:

ARMELS TRANSPORT LTD.

BENNIN CITY: ONITSHA: ABA:


## Minisita Kan Je Gbese

EKO— Awon Oyinbo onisowo kan ti nwon nta moto l'Eko ti oruko ise won nje Matzen and Timm ti gbe Minisita alabojuto ise Ijoba Apapose lo siwaju adajo Kotu-ganran fun gbese ti o je. Oruko Minisita na ni Dokita E.A. Esin.

Awon Oyinbo onigbese Minisita yi ni owo ti o je awon nlo si bi nkan bi egbedogbon poun lori awon moto akeru ti o ra lowo awon ni awin, ti o si sowipe on a ma san owo won die die.

Awon Iwe Asiko:

# Aggrey Omo Ilu Afrika (2)

## Lati Inuwe ALUFA ATILADE

Eleyi ni apa keji itan igbesiaye Dokita J. K. Aggrey, ọmọ ilu Aganyin ti o ṣe bẹbẹ ninu ẹkọ giga awọn enia-dudu Iwọ Orun Afrika. A da iwe yi lati inu iwe Alufa (Rev.) E. A. Atilade ti a npe ni AKỌKA YORUBA (apa karun) ti ẹ le ri ra ni No. 6, Aṣabi Street, (Ogunmokun Road), Mushin, tabi ti ẹ ba fi kọ iwa ra a ninu apoti iwe P. O. Box 263, Ebute-Metta Ẹ ma ka itan na niṣo:

Lẹhin igbati o ti jade kuro ni ile ẹkọ giga yi, o di Oniwasu ati olukọ ni ile ẹkọ ti a npe ni Livingstone College ni ilu North Caroline ni Amẹrika. Nigbati o wa ni ile ẹkọ yi, o bẹ ọpọlọpọ awọn enia dudu ti nwọn wa ni Amẹrika wo, o 'si ri i pe ọpọlọpọ won jẹ talaka ati pe nwọn fẹ iranlọwọ ati igbinyanju nipa ẹkọ.

Aggrey lọ sọdọ awọn enia wọnyi, o si nlọ gbe arin wọn lati gba wọn ni iyanju nipa ọrọ ati apẹrẹ.

Ni akoko yi ni obirin ọlọrọ kan ku ni Amerika ti o si fi ọpọlọpọ owo silẹ pe ki nwọn lo owo na lati fi kọ ẹkọ nipa ọna ti o dara julọ ti a fi le ran awọn enia ilẹ Afrika lọwọ.

Lati mu ifẹ obinrin yi ṣẹ, awọn ẹgbẹ arinrin ajo kan mura lati lọ si Ilẹ Afrika lati lọ kọ bi awọn Enia Dudu ti ngbe ni ilẹ wọn. Olori ẹgbẹ yi gburo iṣe ti Aggrey nṣe larin awọn Enia Dudu ti o wa ni Amẹrika o si pe e lati jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ arinrinajo na. Inu Aggrey dun lati gba ipe yi.

Fun nkan bi ọdun mẹta ni Aggrey pẹlu awọn ẹlẹgbẹ rẹ yi fi rin irin-ajo s'oke s'odo Ilẹ Afrika Aggrey nikan lo jẹ enia dudu larin awọn arinrinajo na. Gbogbo Ila Orun Afrika, Iwọ Orun Afrika, Ariwa ati Gusu Afrika ati arin Afrika ni nwọn wọ kakiri, nwọn si kọ ẹkọ ọpọlọpọ nipa awọn enia ilẹ na.

Nigbati awọn arinrinajo wọnyi de Ghana ni ọdun 1920, inu awọn ara ilu dun pupọ lati ri eruku wọn atijọ ati ọmọ ọkan ninu awọn iyoye wọn. Nwọn ki Kabọ bi ọmọ ọba wọn, nwọn si bẹ ẹ pe ki o ranṣẹ pe aya rẹ lati Amẹrika, ki o duro larin wọn lati ma ṣe oluko wọn: ṣugbọn Aggrey ko le fi awọn ẹlẹgbẹ rẹ silẹ laiba wọn pada lọ si Amẹrika.

Gomina ti Ghana, Sir Gordon Guggisberg jẹ enia rere, o si fẹ fi ohun ibukun kan silẹ fun awọn ara Ghana. O mọ pe ohun ti awọn ara Ghana fẹ lati le jẹki nwọn mọ bi a ti le le ọpọlọpọ ọrọ ti Ọlọrun fun won ni ẹkọ giga. Gomina oninure yi wa eto kikọ ile ẹkọ giga le'lẹ. Nigbati nwọn bere si ronu nipa awọn olukọ ti o yẹ fun ile ẹkọ na, nwọn ranti Aggrey, nwọn ranṣẹ pe e lati Amẹrika.

(iyoku di ọsẹ ti mbọ)

# Iya Alufa Atilade Jalaisi

MUSHIN — O ya wa lẹnu lati gbọ iku Iyaafin Dorcas Oyeronkẹ Atilade ti o jalaisi ni ọsẹ ti o kọja yi ninu ile akobi ọmọ rẹ, Alufa E.A. Atilade ni 6, Ashabi Street, Mushin; ẹni adọrun ọdun ni ologbe ipa na, o si jẹ ẹniti o ni ifẹ enia lọkan nigba aiyẹ rẹ.

Gbara ti nwọn ti tufọ iya na ni awọn ọmọ'loku ti bẹrẹsi na'wo na'ra, Aisun ti awọn ṣe fun oku na kamama, gbogbo awọn enia pataki pataki ni nwọn pe silẹ patapata.

Ni kutukutu owurọ ọjọ keji ni nwọn gbe oku iya na lọ si ilu rẹ ni Awẹ leti Ọyọ lati lọ sin; ninu ile isin Ijọ Christ Baptist Church ni nwọn ti se isin ikẹhin fun iya ouinure yi. Gbogbo awọn enia lati Eko, Abẹokuta, Ibadan ati Ọyọ ni nwọn wa si ibi isinku na.

A ki awọn ọmọ'loku, awọn bi Eni-ọwọ Alufa E. A. Atilade, Ọgbẹni J.A Atilade, ọga ile iṣẹ Atironkẹ Brothers Bookshop ti Agbeni ni Ibadan, Iyaafin Joko Adesile ati awọn ọmọ ọmọ oloku, awọn bi Loya Paul Atilade, nwọn ku aṣẹhinde Oluwa ki o da awọn ti o ku si.

# Irohin Soki Kakiri Agbaiye

## Obinrin Russia Kan Lo Sorun

MOSCOW—Awọn ara ilu Russia ju obinrin kinni ti yio kẹ lọ si ibiti ẹlemi kan ko de ninu awọ-sanmọ si oke ọrun ni ọjọ Jimọ (Friday) ti o kọja yi Oruko obinrin na ni Ọmọge Valentina Tereshkova, ẹni ọdun mẹrindinlogbọn bise.

Awọn Onirohin ilu Russia ni obinrin na tẹ waya lati oke sanma si awọn ara ilu Russia ati Olotu ilu na, o si sọ fun wọn wipe alafia ni on wa, nkan si nlọ dede fun on.

## Peau Okunrin Kan

Awọn Russia alagbara ti o fi ẹrọ ju obinrin si oju ọrun ni awọn ti ju okunrin kan ti oruko rẹ nje Colonel Valery Bykovsky saju si oju sanmọ na, boya awọn le jọ ba ara wọn pade loke na, ki nwọn si jọ sọrọ pọ.

Onirohin kan ni gbogbo awọn ara ilu Russia ni nwọn ri aworan ọmobinrin nini ọkọ ti o gbee lọ sọrun.

## Isinku Evers Dun

JACKSON — Ẹyẹ isinku ọkunrin alawọdudu Medgar Evers, ti awọn janduku Oyinbo Amẹrika yinbọn pa nitoripe o wa ninu awọn ti o nfẹ yọ awọn ẹgbẹ rẹ ninu ajaga inunibini nwọn nṣe si wọn, dun pupọ lọjọ ti nwọn ngbee lọ si ilu Washington lati sin in.

Ṣugbọn ki nwọn to gbee de idi ọkọ ti yio ru ọkọ na lọ si ilu Washington ni awọn janduku Oyinbo alawọ funfun kan tun fẹ gbe ija ko awọn oloku na; awọn ọlọpa ni nwọn dẹrọ ija na, pẹlu kunmọ ati opa wọn.

Ju gbogbo rẹ lọ, nwọn tun yinbọn fun ọdọmọde alawọdudu kan, ṣugbọn awọn dokita tete fa ọta na yọ lọrun rẹ.

Ọrọ opa'laiye awọn alawọdudu na pẹlu awọn Oyinbo Amẹrika ko ti dẹrọ rara ṣugbọn bale ilu Amẹrika Ọgbẹni Kennedy fẹ gbe ofin kan tuntun jade lori ọrọ awọn janduku na

# ELETI–OFE

A NJU WỌN KÔ ṢE WI LẸJỌ

EDITORIL OFFICE & WORKS 28, Kosọkọ Street, Lagos, CABLE & TELEGRAMS "ELETI-ỌFẸ" LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO. 874 SATURDY JUNE 22 — JUNE 28 1963


Oro Olotu:

## Awa De?

Ẹnikẹni ki jẹ awa de. A ti ma ngbọ iru ọrọ bayi lati ẹnu awọn baba wa ti pẹ. Irohin kan ti a ri gbọ lati ọdọ awọn onirohin wa wipe awọn alamojuto Ijọba ilu Aganyin, ti nwọn ti fi igba kan ṣe ofin wipe enikan ko gbọdọ ka iwe irohin ilu Nigeria mọ ti ka ofin na kuro lo jẹ ki a sọ ọrọ waasi wa ti ọsẹ yi ni awa de.

Inu wa dun lati ṣe akiyesi wipe nkan ṣe nrọ diẹdiẹ lọdọ awọn aladugbo wa ni Oke Okun si daradara.

## Gbogbo Aiye

Aiye ti lu jara wọn nisisiyi, ko si eniti ko mo wipe gbogbo agbaiye ni nwọn fẹ mọ nkan ti awọn aladugbo wọn nṣe nibomiran. Ko si bi a ti le fọwọ bo wọn lẹnu

## Omo Ilu-Tangayika



Aworan yi ni ti ọmọ ilu Tanganyika ti Ijọba ilu na ran lọ si ilu Oyinbo lati lọ kọ bi nwọn ti nfi ẹrọ ṣe iṣiro owo, Ọgbẹni Eliya Kanyagha na ni o duro ti ọmọbinrin kan ti o nfi hi ẹrọ na ṣe iṣiro han an yi.

# Iwe Si Olotu

## Alagbara Ma Mero

Ẹ jọwọ alagba, mo gba fun ọrọ yin ti ẹ fi ṣe ikilọ fun wa ninu iwe irohin Eleti-Ọfẹ ti ọsẹ ti o kọja ti e sọ wipe awọn enia kan wa ti o yẹ ki a ma pe oruko wọn ni ỌBỌ NI YIO P'ARA RẸ.

Ọrọ yin na dara pupọ o si tọka nkan ti o mbọ nilu wa fun awọn ti nwọn moye. Suna tabi adinni ti a ba fun iru awọn alaini ironu ti nwọn ni awọn lagbara, ti nwọn ko le lọ fun ire ilu awọn ara ilu wọn afi fun iparun ni BABA ALAGBARA MA MERO.

Nitotọ ni ọrọ iwe Alufa Atilade ti o ni bi a ba jaja gbe nwọn sipo agbara, nwọn a beresi fi ipo na ṣe jamba fẹlẹgbẹ wọn.

Abọ ọrọ ti to fun awọn ti nwọn mọ oye, Olotu, mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni,

Oke Fọkọ, Ibadan. A. Adedokun

## Owo Riba Ko Dara

Olotu, laipẹ yi ni ẹ kọ iwe ikilọ kan fun wa ninu iwe irohin yin Eleti-Ọfẹ wipe owo riba ti awọn ara ma ngba yẹn ko dara rara. Mo gbadun ọrọ yin ti ẹ fi si wa leti na, ṣugbọn otitọ ọrọ bi isọkusọ ni o ma nri loju awa ara aiye.

Ọpọlọpọ awọn enia ni aiye wa ti ode nisisiyi ko ni igbagbọ si wipe ti enikan ba wa nipo nla ki o mọ gba owo-riba nitoripe owo yi ni nwọn fi ngbera,

Awọn ti o wa nipo nla ni ọrọ na mba wi, Olotu, ṣugbọn o yẹ ki a ma ṣe ikede rẹ ni Ṣọṣi ati Mọsalasi fun awọn enia wa ki o ba ma wọ wọn lẹwu.

Emi ni,

Jacob Ọla
(Ọmọ Iludun)

# Pa Pearse Jalaisi L'Eko

EKO—Aku ṣe wa lati tufọ Ọgbẹni Ezekiel Abiọsẹ Pearse, eni ti gbogbo awọn ara Eko ma npe adape oruko rẹ ni Baba Onilutiriki nigba aiye rẹ; eni odun mejidilogorin ni ogbẹni wa na ki o to jalaisi ni alẹ ọjọ Aiku (Sunday) ti o kọja yi ninu ile rẹ ni popo Layeni ni ita Akinni.

( Wo yoku loju ewe karun )

Oro Olotu

to, otitọ ni lati jade lọjọ kan dandan.

Nitotọ oni iwe awọn irohin ilu yi ko fi igba kan gbọ ibẹrẹ fun Ijọba kijọba, nwọn ko nfi ọwọ bọ ẹnu lati tako ilebe awọn alakoso Ijọba fun wọn. Iru eyi ni a ro wipe a bi Ọgbẹni wa, Dokita Kwami Nkrumah ninu ti o fi wipe on ko gbọdọ gburo iwe wa mọ rara lojude on.

Ṣe enikan ki jẹ AWA DE. Bi awọn Olotuwa ba lema fi apẹrẹ ti awọn oṣelu ilu Oyinbo, ti nwọn nfi suru ati lakaye ba awọn ara ilu lo, nkan yio ma lọ dede.

Lẹkan si, a tun sọ fun awọn aladugbo wa, enia kan ko njẹ awa de; bi a ba le ma jẹki awọn ti o nri ipakọ wa sọ nkan ti nwọn ri nibẹ fun wa aiye a ma lọ de.

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

### Lati Owo Ayiluka

## Odun Egungun

Ẹnyin ara mi ofin awọn Oloyinbo ko tilẹ si ẹniti ko tilẹ si ẹniti ko le mu ni aiye ti a wa yi, o mu baba elegun l'ọjọba, o mu egungun rẹ pẹlu. Mo gbọ wipe awọn ọlọpa ti ṣe ikilọ wipe awọn ara Ibadan ko gbọdọ ṣegungun lọtẹ yi nitori nkan ti o wa nilẹ yi.

Mo gbọ wipe egungun ALAPASANPA ko ni jade ni ọdun yi; awọn ara oko ti nwọn ru ogunlọgọ atori wa si ỌJABA ko ni ri ẹni kan ra wọn. Ẹwa - ere paapa a dinwo ni Ọ;a Dugbẹ. Kinni o fa a, ofin Ijọba ti nwọn ṣe wipe ki onile gbe ile ni.

Ni ile Olubadan ni Alafara, nwọn ni Olubadan paapa ti ṣe ikede wipe awọn elegun kan ki o ma wa ki on titi ti ofin onilegbele yio fi kẹsẹ nilẹ.

Ọrọ ti Olubadan na sọ fẹrẹ bi awọn elegungun ara oko Ibadan ninu, sugbọn b a b-a wa Olubadan mọ wipe a ni lati bẹru ofin ijọba.

## Ololu

Aiye"nlọ a ntọ, ṣe o wa jẹ wipe egungun ti a pe ni OLOLU ko ni jade ninu ọdun yi ni Ibadan ? Ko si wipe a ndin akara ati ọlẹlẹ mọ ni ile awọn Abegunde ni Opopo Yeọsa.

## Awon Onisiga

Awọn kan ti da ẹgbẹ ma-mu-siga silẹ ni ilu Oyinbo. Ko si wipe a nfi owo wọ ẹgbẹ na, nibẹ sugbọn ti o ko ba ti le mu siga mọ ọrọ ti buse. Mo gbọ wipe awọn ọdọmọde kan fẹ da ẹka ẹgbẹ na silẹ ni Nigeria ni apa Kano ati ni Ibadan, Nwọn n i siga mimu nko arun ọgbẹ inu ba enia.

**Awọn onisowo ti nwọn nta siga paapa ti gba dokita** ti o mọ iṣẹ nipa egbo-inu ti nwọn npe **orukọ rẹ ni** Cancer lati so fun awọn araiye pe ko si ewu ninu siga mimu rara.

## Oba Kano

Mo ba Ọba Kano tuntun ti nwọn ne Lawan fun ni ijẹta yọ. Mo gbọ wipe o to irinwo ẹṣin ti nwọn fi ṣe ẹyẹ fun ọba na. Awọn dongari ọlọpa paapa dabira nibi Oye na.

# Pearse Jala-isi L'eko

( O bẹrẹ loju ewe kẹrin )

Ni igba aiye rẹ iṣẹ a mba nwọn to ina ilẹtiriki (ina onimanamana) mọ ile ni o nṣe, o si jẹ ọkan ninu awọn ti o ko fi iṣe na ṣe ọla.

Ni ijẹrin ọjọ Wednesday ni nwọn sinku rẹ. Ṣọṣi ti nwọn npe ni Christ Church Cathedral l'Ẹhingbẹti l'Eko ni nwọn gbe e lọ ki nwọn to lọ sin in si itẹ Ikoyi.

A ki awọn ọmọ ti ologbe na fi silẹ, awọn Iyaafin Titi aya Dokita ENO Ṣodeinde ati ọmọge B. Pearse, ti o nṣiṣẹ ni ile awọn agbẹbi ni Eko ; pe nwọn ku aṣẹhinde.


# E Ka Oro Olotu loju Ewe Kerin.


# Enia Dudu Ni Ile Eko



**Gbogbo awon agbaiye ni nwon nran omo won wa ko eko ni ilewe awon Oyinbo ni ilu Gesi. Awon omo ilu Nigeria ati Ghana ni nwon wa ninu ile iwe ni London nibiti obinrin tisa kan gbe ti nko won leko yi.**

## Eleti—Ofe D'araba

# Awon Elewon Faake Kori Lori Oro Kirikiri

EKO — Şangba tun fọ ni ọgba awọn ẹlẹwọn l'Eko ni ijẹrin nigbati awọn janduku ẹlẹwọn faake kọri wipe ko si ẹniti o le şi awọn nipo pada rara, nwọn ni awọn ko fẹ lọ si ile ẹwọn tuntun ti nwọn sẹsẹ kọ si Apapa ti awọn npe ni KIRIKIRI.

Onirohin wa ni o to oşu kan nisisiyi ti ijangbọn awọn ẹlẹwọn na kọ bẹrẹ lori onjẹ ko şe onjẹ ti nwọn ko fun awọn jẹ to; nwọn ni ẹlẹwọn kan ti orukọ rẹ njẹ BABA ALAGBARA (Mighty Joe) ni o da ijangbọn yi silẹ.

Nwọn ni bi nwọn ti fun awọn ẹlẹwọn yi ni onjẹ ọsan tan ni ẹlẹwọn BABA ALAGBARA yi ba wọ ọjẹ-onjẹ lọ ni o lọ fi agbara gba onjẹ lọwọ awọn ti o ọşe onjẹ na. O gbe ija ko dẹrẹba ẹlẹwọn ti o fẹ dą a duro wipe ki o ma gba onjẹ na.

Eleyi ni o mu ija igboro ti akokọ wa fun awọn ẹlẹna, sugbọn nwọn ni ki ọga ile ẹlẹwọn lọ şe iwadi ọrọ ti o fa ijangbọn na silẹ.

Ijangbọn ti ijarun yi bẹrẹ lori iwadi ti nwọn sọ wipe awọn ọga-ẹlẹwọn na ti şe iwadi na pọ sibi kan. A gbọ wipe ni owurọ ijarun ni awọn gbe moto wa si ẹnu ọna ọgba ẹwọn ni Eko, nwọn si sa awọn ẹlẹwọn mẹdogun ti nwọn pe ni awọn olori janduku, nwọn ni ki nwọn bọ sinu moto ki awọn ko wọn lọ si KIRIKIRI.

Eleyi mu awọn ẹlẹwọn na binu patapata, nwọn ni awọn ko lọ si ibi kan rara. Ija ọjọ na pọ pupọ diẹ nitoripe awọn dẹrẹba ẹlẹwọn mẹa ni wọn gun lọbẹ ni gunkugun.

Awọn ọga ile ẹwọn na ni lati kesi awọn Ọlọpa wipe ki nwọn ba wọn dẹ rọ ija na gbogbo awọn janduku ẹlẹwọn yi ni nwọn ti ko lọ sinu AJA-ile ti nwọn kọ fun awọn janduku ẹlẹwọn ni Kirikiri ni Apapa.

## Oloye Abudu Smith Sinku Iya Re



Oloye ABUDU SMITH

Gbogbo awọn Imale Eko ni nwọn pe si ibi isinku Iyalfin Sadatu Agbe Smith ẹni ọdun marunlelọgọrun ti o jalaisi ni ile rẹ ni adugbo ti nwọn npe ni Idita ˆmọ Offin l'Eko ni ijẹfa. Iya Oloye Abudu Smith, Osi Eko ni Ologbe na nşe, o si fẹ jẹ wipe on ni o ku ninu awọn obinrin ti o dagba ju ni Offin.

Lemamu Mọsalasi Idita ni o kewu si oku na lara, ki nwọn to gbe e lọ si itẹ. Awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ ki awọn ẹmọloku ku aşehinde, ọjọ yio jinde si ara wọn.

E Polowo Oja Nyin Sinu Iwe Irohin Eleti Ofe Losose

## Awon Oniwe Ironin Nilu Oyinbo



Aworan yi ni ti awon akowe oniwe irohin merin ara ilu Tanganyinka ti awon ara ilu Oyinbo gba ni alejo nigbati nwon nse ibewo ero ti awon Oyinbo fi nroko ninu oko won. Oyinbo kan ti nwon npe ni R. D. Thomas, akowe ile ise irohin Ijoba Gesi ni Bristol ni o wa ni ipo keji lati apa otun aworan yi. on na ni o si nse atoka gbogbo nkan ti awon oniwe irohin na nwo kiri fun won.

# East And West African Ministers Meet In London

LONDON — A meeting of two old friends-Nigeria's Federal Minister of Finance, Chief Festus Okotie-Eboh, and Kenya's Minister, of Justice and Constitutional Affairs, Mr. Tom M'boya took place on the steps of the Commonwealth Relations Office in London yesterday.

The Nigerian Minister was just leaving the C. R. O. after talks with Mr. Duncan Sandys' Secretary of State for Commonwealth Relations and the Colonies, as Mr. M'boya, heading the three-man Kenya delegation now in London, arrived.

"I was delighted to see Mr. M'boya again, for we are old friends," Cheif Festus told our correspondent shortly afterwards.

Chief Festus has now completed his talks with British Government Ministers about Nigeria's Development Plan and is spending the rest of the week meeting British industrialists and businessmen.

## Nigerian Women See Road Safety Training

LONDON—A party of Northern Nigerian women now touring Britain watched fascinated as policewomen in Manchester showed them how train children in road asfety with the aid of puppets.

The women have been visiting Manchester during a month's tour of Britain as guests of the British Council. They leave today for Glasgow to visit hospitals and see something of women's voluntary societies.

In the party are Malam Habiba Kaile, wife of the Minister of Educatin; Malama Aishatu Hajiya, wife of the Northern Minister of Finance; Mrs Agnes Ebun Ajayi, wife of the Minister of State in the Premier's Office; Mrs. Ayo Edun, a midwife; Mrs. Mariyamu Dinka, wife of the District Superintendent of Police, Zaria Province; Mrs Grace Amego a social welfare officer; Malama Falmata Mani, matron of the GirlsSecondary School, Maiduguri; Miss Naomi Timothy, a teacher at S. I. M., Kwoi; Malama Amina Ibrahim, a teacher in Sokoto N. A., and Miss Barikisu Mohammed, a student nurse.

At the Manchester city police headquarters, the visitors watched the puppet demostration in the traffic department. Two women police specialists use the puppets to show school children how they should behave on the road. The visitors also went to a school for deaf children, and to a children's home, while in Manchester.

## Call For A World Society

LOS ANGLES (ISI) President Radhakrishnan, now visiting United States, did sightseein in Los Angeles, California and was guest of honour at a dinner given by the Motion Pictures Association of America.

Earlier the President President visited Disneyland and spent about three hours in the amusementnt park. Walt Disney personally took the President around.

Speaking at a dinner given to him by the World Affairs Council in Los Angeles, Radhakrishnan called for a world society and a world community that will value humanity above all nations. He said that nation states must surrended some of their sovereignty to a world authority vested with the power to settle disputes according to justice if the world is to be saved from destruction.

Radhakrishnan said 'We must surrender our right to private violence. It will be a constant source of unrest if people are treated on a fair basis or are submerged. All citizens should have the right to express themselves' The President said: "We need a community of ideas to bring citizens together. Private armies should be eliminated and economic conflicts removed."

## Dick Tiger Award Applauded



LONDON — Under the headline 'Tiger, MBE', the British leading boxing newspaper 'Boxing News' in its latest issue applauds the recognition given to Dick Tiger, Nigeria's World middleweight chanpion, in the Queen's Birthday Honours list.

The paper comments: 'This is a fine boost for Nigeria, the Commonwealth and for the sport itself. With so much adverse publicity regarding boxing from time to time this recognition does prove that success in the noble art is noted when honours are being handed out."

# Egungun Wole Ni Ilu Ibadan

( O bẹrẹ loju ewe kinni)

Gẹgẹbi a ti gbọ irohin na lati ọdọ onirohin wa, a gbọ wipe lọjọ Aje ti o lọ yi ni awọn ara Ibadan ni lati bẹrẹ ọdun egungun wọn ti nwọn ma nṣe lọdọdun. Gbogbo awọn ara oko ni nwọn si wa sile fun ọdun na.

Alẹ ọjọ ti nwọn ngbe AGAAN (aisun egungnn) ni awọn gbọ ti awọn akọwe iṣẹ Ijọba nṣe ikedẹ ninu ẹrọ asọrọ-magbesi (redio) wipe awọn ko gbọdọ ri ọjẹ kan ko mu egungun jade.

Ọrọ na ba gbogbo awọn ọjẹ ni abo nitoripe ọpọlọpọ awọn iyawo ati ọmọ wọn ni nwọn ti da aṣọ orişirişi ti nwọn fẹ fi ṣe ẹyẹ ọdun eguugun na. Awọn miran si ti pa adiẹ jaburata silẹ.

## Alapansanpa

Ni irọlẹ Ọjọ Aje (Monday) eegun ti nwọn npe ni Alapansanpa jade pẹlu awọn ọmọlẹhin rẹ ati awọn onilu, o bẹrẹsi jo ijo ọdun ti o ma njo gba Bẹrẹ, Ọjagbo, Ọranyan ati Alafara lọ.

Ni nkan bi agogo marun irọlẹ ni o ya bara lati lọ fori ba ilẹ fun Olubadan ninu ile rẹ ni Alafara gẹgẹbi eegun Alapansanpa na ti nma nṣe ni ọdọdun.

Bi o ti ku diẹ ki o de ojude Olubadan ni o ri ogenlọgọ awọn ọlọpa ati awọn akọda ti nwọn da a duro.

Eeguu yi kọ lati pada sẹhin, o ni a fi bi on ba foju kan Ọba Akinyẹle ki on mọ nkan ti o wọ ilu Ibadan ti nwọn fi 'sọ wipe nwọn ko fẹ ri eegun mọ. Alapansanpa ni irọrun ni awọn nfẹ fun ilu.

Mo gbọ wipe ọpalaiye ti ọrọ egungun yi ba awọn oṣelu wi ati pe ikunsinu wa lori alaga ile igbimọ Ijọba ibilẹ Ibadan, Ọgbẹni A. M. A. Akinloye. Awọn kan ni on ni o gba awọn ọlọpa ni imọran wipe ki nwọn ṣe ofin ki onflegbele ki awọn ọjẹ ma ba le mu eegun kankan jade.

Awọn kan ni ni iwọn ọdun keji sẹhin, nigbati Ọgbẹni Akinloye wa ninu awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu AG. on ni o kọ ọmọlẹhin saju eegun Alapansanpa yi, ti gbogbo wọn njo kakiri ilu Ibadan.

A ko ti mọ iru ẹjọ ti awọn ọlọpa fẹ ba awọn ọjẹ mẹtadinlọgbọn pẹlu eegun wọn ti nwọn ko nita nibiti nwọn gbe njo kiri ro, sugbọn mo gbọ wipe nwọn ti da wọn silẹ pe ki nwọn ma lọ si ile wọn, awọn ko gbọdọ ri eegun kan nita pẹlu awọn eni lẹhin rẹ mọ.

# Tafa Fomo Odun Metala F'oko

(O bere loju ewe kinni)

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ, nigbati ọmọ yi, Fatumọ, ti wa ni ọmọ ọdun mẹwa, ti o nlọ si ile iwe ni Bauchi ni ọkọ rẹ yi ti nfẹ ẹ sọna, ti o si ti toro rẹ lọwọ awọn obi rẹ.

Alhaji Yakubu, ọkọ iyawo ọlọwọ aro yi ti'ni awọn obinrin ẹlẹha mẹta kan nile ti nwọn yio jẹ iyale fun eyiti o ṣẹṣẹ gbẹ yi. Mo gbọ wipe ẹlẹha ni ọkọ Fatumọ yio fii ṣe.

Lawo ti baba iyawo, Ọlọla Tafawa Balewa, na lọjọ na pọ, bẹsini iya iyawo na ti njẹ Senabu ati awọn ẹlẹha orogun rẹ mẹtẹta. Malu meji ti nwọn tobi fakiya ni baba iyawo ta le awọn ọlọpa ti nwọn wa si ibi iyawo na lọwọ wipe ki nwọn pa, ki nwọn se, ki gbogbo wọn jẹ ati iyawo wọn pẹlu ọmọ wọn.

Bayi ni a nṣe nile wa, ewọ ni o jẹ nilu awọn ẹlomiran; ko nṣe nkan ti oju ko riri lati fọmọ ọdun mẹtala lọkọ nilẹ awọn Hausa rara.

# IYAWO ALARADE PREST KOKO RE SILE

(O bere loju ewe kinni)



ran ọjọ kan ti awọn jọ ngbe ni Mushin ti ọkọ on ru ale obinrin ka wa ba on. Nwọn npe obinrin na ni Tsataje, o ni ẹnikeji ti on fẹ le on niyi.

Obinrin alarede na ni lọjọ kan ti on ti ibiṣẹ de ni on ri wipe ọkọ on ti ko ẹru rẹ lọ si ibomiran pẹlu iyawo tuntun na. O ni on wa wọn titi on fi ri wipe ile ẹdọ Kọra kan ni nwọn ko lọ ti nwọn nlọ gbe.

Alarede iyawo na ni on ko tọ wọn lọ, on si ni ki o le obinrin ale rẹ na jade fun on, o kọ jalẹ. O ni obinrin na ti ba ọkọ on lọ silu Oyinbo, o si bi ọmọ meji fun un.

# Awon Ijo Aguda

(O bere loju ewe ekinni)

CORDINAL MONTINI ni oruko eniti nwọn pejọ yan na ..., eni ọdun marunlelọgọta ni-... si ni Archbishop ilu Milan ni Itali. A gbọ wipe on ni yio kọ jẹ Pope kinni ti ko dagba pupọ ki o to gun ori oye.

Ni ọdun ti o Kọja ni Pope tuntun yi wa yẹ awọn Ijọ Aguda wo ni ilẹ Nigeria o ... se bebẹ Ni Ibadan. O ni Pope PAUL Kefa ni oruko ti on fẹ ki nwọn ma pe o kakiri agbaye.

A ki ẹnyin Ijọ Aguda, ẹ ku orire ki asiko Pope tuntun na ki o san wa.

# Eleti-ofe D'araba

Printed and Published by The Union Brinting and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street, Lagos, Box 467 Phone 23370; Edito.: (Olotu) Ọla. Ọnatade, 15,Kosọkọ Street, Lagos